ÈDÈ

JOURNAL OF LINGUISTICS, LITERATURE & CULTURE



DEPARTMENT OF LINGUISTICS & NIGERIAN LANGUAGES,
UNIVERSITY OF ILORIN, ILORIN, NIGERIA

VOL. 1, 2008

COPYRIGHT

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced by any means, nor translated into any other language, without prior written permission from the copyright owners.

Printed by: Unilorin Press

ÈDÈ: Journal of Linguistics, Literature and Culture publishes papers of about fifteen pages, including an abstract of not more than 100-150 words. As the title of the journal suggests, the journal publishes papers from all aspects of linguistics, literature and culture of any natural language.

EDITORIAL CONSULTANTS
Prof. Bade Ajuwon
Prof. I.O. Alaba
Prof. Tunde Ajiboye
Prof. Bayo Lawal
Prof. Gbenga Fakuade
Prof. Francis Egbokhare
Dr. Duro Adeleke
Dr. A.H. Amfani

EDITORIAL BOARD
Editor-in-Chief
Y.A. Ajayi

Managing Editor
Issa O. Sanusi

Members
M.A. O. Oyebola
R.K. Omoloso
S.A. Aje
J.A. Atoyebi
B.E. Arokoyo

Subscription rates

Per Annum:	NIGERIA	USA	CANADA	UK	EUROPE
Individuals	N600.00k	$18.00	C$30.00	£12.00	$18.00
Institutions	N800.00k	$25.00	C$38.00	£20.00	$25.00

All orders and remittances should be sent to the Managing Editor, **ÈDÈ: Journal of Linguistics, Literature and Culture,** Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilorin, P.M.B. 1515, Ilorin, Nigeria.

Ogunbiyi, I.A. (1984) 'Arabic loan words in the Yoruba Language in the Right of Arab /Yoruba Relations from Pre- historic times Arab Journal of Language Studies Khartoum.
Ogunbowale, P.O. (1970) The Essentials of the Yoruba Language. London: Hodder & Stoughton.
Ogunshina, P. (1992) *The Development of the Yoruba Novel, 1930 1975*. Ibadan: Gospel Faith Mission Press.
Olatunji, O.O. (1984): *Features of Yoruba Oral Poetry.* Ibadan: Univeristy Press Ltd.
Okpewho, I. (1983) *Myth in Africa*. London: Cambridge University Press.
Shuaib, M.A. (1969) Al- adab ul Muqaran, Cairo, Dannit ta'lif.

ÌSEKÁRÍAYÉ ÀTI ÀSÀ YORÙBÁ: ÀGBÉYÈWÒ EWÌ ÀPILÈKO *AYÉ N YÍPO*

Hezekiah O. Adeosun
Department of Linguistics and Nigerian Languages,
University of Ilorin, Ilorin
hezekiahadeosun@yahoo.com

Àsamò

*Kì í se ohun tuntun tàbí ohun èèwò ni kí àwùjo kan mú lára àbùdá àsà àwùjo mìíràn. Nípasè èyí, ìdàgbàsókè àti ìtèsíwájú nípa ètò oró-ajé, ìsèlú, ìmò èro àti ìmò sáyénsí yóò máa bá irú àwùjo béè. Sùgbón ohun tó burú jái ni kí àsà tí a mú láti ara àbùdá rè kúkú wá gba orí lówó àsà tí a yá a wò. Pàtàkì ohun tí a gbé yèwò nínú isé yìí ni àkóbá tí ètò ìsekáríayé (tàbí ohun tí Adéyemí (2006) pè ní ìso-ayé-dòkan) se fún àsà Yorùbá, pàápàá àsà ìgbéyàwó. A fi ewì àpilèko **Ayé n yípo** tí Àyángbilé àti Òpádòtun ko se àtègùn. A wo ire àti ibi tó wà nínú ìsekáríayé, gégé bí ó se hàn nínú ewì àpìlèko yìí, pèlú ìmòràn ònà àbáyo nípa pípadà sí àsà ìbílè Yorùbá.*

Ìfáàrà

Ní ilè tó mó lónìí, òrò nípa ìsekáríayé tàbí ìso-ayé dòkan gégé bí ìtumò tí Adéyemí (2006:1) fún ohun tí a mò ní èdè Gèésí sí 'globalization', ló gba àyé kan. Èyí tí ó so gbogbo àwùjo omonìyàn pò lágbàáyé nípasè ètò orò ajé, ètò ìsèlú, ìmò èro, èdè, kòmpútà, fóònù alágbeéká àti èro aríhìnínróhùnún gbóhùn-eni (internet). Gbogbo ohun tí ó n selè lágbàáyé ní a lè rí kedere nínú iyàrá wa ní ìgbàkugbà ti ó bá wù wá láti rí i. Èniyàn lè bá òré àti ojúlùmò rè tí ó wà ní òkè òkun sòrò kí wón sì máa rí ara won.

Àwon nnkan wònyí jé ara ànfàání tí ìso-ayé-dòkan mú wá sí ilè adúláwò, pàápàá julo ilè Naijiria, tí àwon ohun báyìí se àjèjí sí télè rí. Sé Yorùbá bò, wón ní tibi-tire ni a dá ilé aye. Bí èrò ìsekáríayé se dára ní àáyè tirè ní ònà kan, béè ni ó mú àkùdé bá púpò lára àsà ìbágbépò àwùjo Yorùbá. Bí àpeere, omo Yorùbá ti jogun àsà kónkójabale, kálukú-ni-n-se tire láti inú àsà Oyìnbó, ní èyí tí ó sàjéjì sí àsà ìbágbépò Yorùbá. Béè sì ni omo Yorùbá kò fèran àsà àti

èdè rè mó. Èdè abínibí rè ti di ohun ìtíjú fún un láti máa so; àsà abínibí rè ti di àsà ará oko àti aláilajú.

Púpò lára àsà tí ó gba àwùjo Yorùbá kan tí ó sì jé gbòngbò fún ìwà ìbàjé lónìí ni ó wáyé láti ara ohun tí a pè ní ìmúnisìn òtun, èyí tí àdàpè re n jé ìso-ayé-dòkan tàbí ìsekáríayé.

Nínú isé yìí ni a ó ti fidí rè múlè pé ìbí kò ju ìbí, bí a se bí erú ni a bí omo. Kò sí àwùjo tí kò ní àsà tire, béè sì ni àsà àwùjo kan kò dára ju ti àwùjo mìíràn lo. A ó tún fi kún un wí pé kò sí àsà àwùjo tí ó tó tán ní àáye ara rè, láímú lára àbùdá àsà àwújo mìíràn, èyí tí ó n fa àyípadà àsà.

Àsà ati Àwùjo

Orísirísi oríkì ni àwon onímò nípa ìmò ìbágbépò àwùjo ti fún ohun tí a mò sí àsà. Lára oríkì béè ni èyi ti Sanderson (1988) nínú Atemie àti Girigiri (2006:1) fún àsà gégé bí àpapò àbùdá ìgbé ayé àwon èda èèyàn àwùjo kan. Lára èyí ni a ti rí àwon nnkan bí ohun èlò, ìmò àtí àlàkalè ònà tí wón n gbà ronú tàbí tí won n gbà se nnkan láàárín ara won, ti ó sì n ràn láti ìran kan sí ìran mìíràn.

Irú oríkì yìí kan náà ni Anele (2006:139) fún àsà nígbà tí ó so pè:

> Culture is that a complex whole which includes knowledge, belief art, law, morale, custom and other capabilities and habits acquired by man as a member of society.

Ohun tí èyí túmò sí ni pé:

> ohun tí ó gbòòrò púpò ni àsà jé. Àkòónú rè sì je mó ímo, igbàgbó, isé-onà, òfin, ìsírí, ònà ìgbà-se-nnkan àti àwon nnkan bí ìse tí èdá èèyàn kó gégé bí ara àwùjo béè.

Síwájú sí i, Àjàyí (2001:107) náà so pé díè nínú àwon nnkan tí ó para pò jé àsà ni èrò, ìgbàgbó, imò, ìkíni, isé, òfin, ìtàn, ìwoso, ìhùwàsí, oúnjé, ètò ìsèlú, orò-ajé, èsìn, ònà ìbàgbépò, èdè, lítírésò... tí won ní ìbásépò pèlú ara won, ní àwùjo kan náà.

Nnkan tí ó se pàtàkì tí a rí fàyo nínú àwon oríkì yìí ni pé àwon èèyan inú àwujo kan ni àsà inú àwùjo béè wà fún. Láisí àwùjo, kò lè sí àsà ti ó so èèyán àti àwùjo béè pò.

Àjàyi (2001) tún tèsíwájú pé ònà mèjì òtòòtò ni àwon onímò nípá ìbàgbépò àwùjo pín àsà sí lágbàáyé:

(1) Ohun tí a fi owó ara wa se, tí a lè fi ojú rí, tí a sì lè gbá mú. Àpeere èyí ni ilé, oúnje, aso, isé onà.

(2) Ohun tí a kò lè rí gbá mú, tí a kò lè fi ojú rí, sùgbón tí á fi okàn ìgbàgbó gbà wí pé ó wà. Àpeere ohun béè ni, òfin, ìtàn, èsín, ìmò, èdé.

Bí ìgbín fà, ikarahun a tèlé e ni àwon èròjà abé ìsòrí àsà méjèèjì jé sí ara won, inú àwùjo ni a sì tí n rí àwon èrojà yìí fún ìlò àwon èèyàn àwùjo béè. Ní pátàki jùlo, bí omi àti aró kò se le yara won, béè ni àsà àti àwùjo rí.

Ohun kan tí ó se pàtàkì tí àwon onímò nípa ìbágbépò àwùjo máa n tenu mó jù ni pé kò sí àwùjo tí ó gbódò so pé àsà àwùjo òun dára jú ti àsà àwùjo mìíran lo. Fún ìdí èyí, wón gbé èrò kan jade, tí wón pè ní 'cultural relativism', èyí tí a túmò sí àsà àparò kan ò ga ju èkejì.

Atemie àti Girigiri (2006:6) so pé:

> Cultural relativism holds that no culture is inherently superior or inferior to others, but that, since every culture constitutes an adaptive solution to fundamental human problems, all culture are equally valid.

> (Ohun ti àsà àparò kan-ò-gà-jú-èkèjì n fúnka mó ni pé kò sí àsà ti ó dára tàbi tó kù díè káàtó ju òmíràn lo, níwòn ìgbà tí àsà àwujo kòókan ti la ònà àbáyo sí ìsòro-kí sòro tó lè súyo láàárín àwùjo béè, gbogbo àsà ni ó kún ojú òsùwòn).

> Àwon onímò tó tèlé èrò yìí fi kún un pé kò seé se kí á fi àsà àwùjo kan se òdiwòn fún àsà àwùjo yòókù nì èyí tí ó túmò sí pé, ìdálùú ni ìsèlú, bí a se n se ní ilú kan èèwò ni ní ìlú ibòmíràn.

Ní ìgbà miíràn, bí ó ti wù kí ó rí, àsà àwùjo a máa yípadà, nítórì pé, àsà kì í se ohún tó dúró rigidi sójú kan bí omí adágún. Bí àpeere, ní àwùjo Yorùbá àtijó, àaye tí àwùjo fi obìnrin sí ni kí ó máa sè ìtòjú ilé nikán, kì í se fún obínrín láti máa sisé òwó ti yóò fi bó ìdílé rè. Ojúse okùnrin tí í sé báálé ilé ni èyí. Èto òrò-ajé àwùjo òde-òní (èto orò ajé aládàánlá) kò fi àaye sílè kí obìnrin jókòó tetere láiní igbá isé kan. Fún idí èyí, tokùnrin tobìnrin ló n sisé àsekára láti tójú ebí wón. Fi òtún we òsì, fi òsì we òtún, ní àsà tó gbayé kan lónìí. Èyí jé àpeere àyípada tó máa n bá àsà àwùjo, tí àwon onímò ìbágbépó àwùjo pè ni 'cultural/social change'.

Àyípadà àsà tàbí èto àwùjo ni Defleur (1977) nínú Anele (2006:139) rí gégé bí:

> ...alterations in the pattern of social organization of specific group within a society or even of the society itself.
>
> (...àyípadà tó máa n bá èto isàkóso egbé kan ní àwùjo tàbí gbogbo èniyàn àwùjo pàápàá fúnra rè).

Irú àyípadà tí à n so yìí máa n hàn nínú ihùwásí àti ìsesí àwon èniyàn inú àwùjo béè. Ìgbàmírán ó lè jé àyípadà sí rere tàbí búrurú, èyí tí yóò lapa lorí èrò àti iyì àwùjo náà.

Orísirisi àyipadà béè ni ó ti wáyé nínú àsà Yorùbá. Bí àpeere, ní ibèrè pèpè, èsìn ìbílè ni a mò mo omo Yorùbá, sùgbón látàrí àyípada tó bá ilè adúláwò, pàápàá ilè Yorùbá, èsìn ìgbàlódé bí èsìn Kìrìsítèni àti èsìn Ìsílámù ti gborí lówó èsìn ìbílè. Ìwònba péréte ni omo Yorùbá tí ó n sin èsìn ìbìlè bí, Òrúnmìlà, Sàngó, Ògún, Obàtálá àti béè béè lo. Ojú aláìmò kan àti kèfèrí ni a sì fi n wo àwon olùsìn

èsìn ìbílè. Ìdájó bóyá irú àyípadà báyìí dára tàbí kò dára, kò sí lówó enìkan, nítórí ohun tó kojú sénikan, èyìn ló ko sí elòmíràn bí ìlù gángan.

Èyí tí ó je wá lógún jùlo nínú àpilekò yìí ni àyípadà tó dé bá àsà ìgbéyàwó láwùjo Yorùbá nípasè ìsekáríayé.

Èrò Ìsekáríayé

Ìsekáríayé, gégé bí oríkì tí ìwe yáágbó-yaájù (Encyclopedia Britannica) (2007) fún un ni:

> Globalization is the process by which the experience of every day life marked by the consumption of commodities and ideas is becoming standardized around the world.
>
> (Ìsekáríayé jé ìgbésè kan tí ó n so ìrírí ojoojúmó èdá, nípasè ìlò ohun ìní àti èrò, di ohun tó n tèlé ìlànà kan gbòógì káàkiri àgbáyé)

Àlàkalè ìlànà kan gbòógì tó n darí ìlò ohun ìní àti èrò káàkìrì àgbáyé yìí níí se pèlú ìdarí èto orò-ajé àti èto ìsèlú orílè-èdè kòòkan lágbàáyé. Èyí túmò sí pé irúfé èto orò ajé, èto ìsèlú, ìmò èro, ìmò sáyénsì, èto èkó àti àsà tí ó bá wà ní àwujo aláwò funfun ni ó gbódò wà ní àwùjo aláwò dúdú.

Robertson (2000) nínú Anthony (2002:1) rí ìsekáríayé gégé bí:

> Crystallization of the entire world as a single place, and the emergence of global human condition.
>
> (àkópò gbogbo ayé àti ipò gbogbo èdá èniyàn sójú kan).

Ohun tí oríkì yìí n tepele mó ni pé ìsekáríayé dá lé kíkó àsà

àti ètò gbogbo ìran èdá ènìyàn lágbàáyé sójú kan, bí a bá se n se ni àwùjo 'A' ni a gbódò máà se ni àwùjo 'B' pèlú. Àléébù nlá gbàá ni èyí jé.

Goddens (1990) nínú Anthony (2002:1) yií kan náà so pé "globalization is a consequence of the tendencies inherent in modernity". Ohun tí Goddens n so níbí ní pé ìsekáríayé tí à n so nípà rè kò sèyìn àtubòtán àsà òlàjú tó gbáyé kan. Èyí ló jé kí àsà àtòhùnrínwá gborí lówó àsà àwùjo adúláwo.

Ìsekáríayé ti wá di ètè tí ó n ràn káàkìrí àgbáyé tí ó n je gàba lórí ìsowó-ronú àwon èyà adúláwò.

Anthony (2001:1) fúnra rè sàpèjúwe ìsekáríayé gégé bí àrùn ètè tó n jà kiri pé:

> It is a vast phenomenon affecting the life style and the thinking pattern of the entire human person in social, economic, political, ecological, cultural, moral, religious and spiritual spheres.
>
> (Ó ti di ohun tí n tàn kale kíákíá, tó fi jé pé ní gbogbo ònà ló ti nípa lórí ìgbèsí ayé èdá ènìyàn bí, ìrònu won, ètò àwùjo, étò orò-ajé, ìsèlú, ìtójú àyíká, àsà, ìwà omolúàbí, èsìn àti ohun tó jé tèmí).

Àlàyé Anthony yií fihàn gbangba pé ìgbé ayé àwon èyà kan ni gbogbo èdá àgbáyé n gbé báyií. Àwon èyà yòókù kò lè dá ronú mó lórí ohun tó ye àwùjo won.

Ní èrò tiwa, ibi tí ìsekáríayé n se fún àwon orílè-èdè tó sese n dìde pò ju ire rè lo. A rí érò yií gege bí ìmúnisìn òtun, níwòn ìgbà tó jé pé àwon orílè-èdè alágbára nípa òrò ìsèlú àti orò-ajé lágbàáyé ló n la ònà tí gbogbo orílè-èdè tó kù làgbàáyé yóò máa tò láti se gbogbo nnkan, béè sì ni ìlànà yií jé fún ànfàání tiwon nìkan soso.

Nínú èrò omo ilè Amériká kan, Joseph Stiglitz tí ó jé alága

ikò tó jé olùdámòràn fún Àare orilé-èdè Amériká nígbà kan, Bill Clinton, ó so nínú ìwè rè tí ó pé ní ***Making Globalization work*** (2006:4) nínú The Guardian (2007:84) pé:

> Economics has been driving globalization... but politics has shaped it. The rules of the game have been set by the advanced industrial countries and particularly by special interests within those countries and, not surprisingly, they have shaped globalization to further their own interest. They have not sought to create a fair set of rules, let alone a set of rules that would promote the well-being of those in the poorest countries in the world.
>
> (Èto orò-ajé ló n satónà isekáríayé... sùgbón ètò ìsèlú ló n se àtúntò rè. Àwon orílè-èdè alágbárá lágbàáyé lo se àlàkalè ìlànà rè, kò sì yàní lénu pé ònà tí isekáríayé yóò fi pé wòn ni wón gbé e gbà. Won kò se àlákalè ìlànà tó se dógbadógba ká máà wá so pé kí wón gbé ìlàna ti yóò wúlò fún àwon orílè-èdè aláìlágbára lágbàáyé kalè).

Àlàyé tí Stiglitz (2006) se yií túbò tan ìmólè sí ípalára tí èrò ìsekáríayé ní lórí àwon orílè-èdè adúláwò àti àsà won. Ìréje àti ìmúnisin ló jé ajólórí èrò ìsekáríayé. Nígbà tí wón bá n sòrò nípa ìsekáríayé ètò orò-ajé (Globalization of economy), ológbò won ò sode nítorí enìkan, bíkòse nítorí enu ara rè. Orísirísi àjo bí àjo ayánilówó àgbáyé 'International Monetary Fund' (IMF) àti Bánkì Àgbáyé (World Bank) ni wón dá sílè látí máa dá kún ìsòro orílè-èdè

kéékèèké tí won yá lówó.

Níwòn ìgbá tí àwon orílè-èdè aláìlágbárá bí ìlè adúláwò kò lè gbìyànjú láti mú ìdàgbàsókè àti ìgbéláruge bá àwon ohun àlùmóónì tí ó wá ní àwùjo won, ohunkóhun tí àwon orílè-èdè alágbára-àgbáyé bá se tàbí tí won rò ni àwon náà yóò mú lò, ti won kò ni í rí ohun tó dára ninú ìse tàbí èrò tiwon mó.

Ìsekáríayé tó ga jù lówólówó báyìí ni èyí tí ó wáyé nípasè ìmò èro kòmpútà, fóònù àlágbèéká, èro-aríhìn-ín-róhùnun-gbóhùn-eni (internet), níbi tí ó ti rorùn láti máa kà tàbí láti máa kó nípa àwon àsà ilè òkèèrè.

Ìsekáríayé Àti Àsà Ìgbéyàwó Láwùjo Yorùbá

Àsà ìgbéyàwó ni àwùjo Yorùbá àtijó jé ohun tí ó lólá, tí ó sì wuyì púpò. Opò onímò nípa àsà Yorùbá ni wón ti sòrò lórí èto ìgbeyàwó ní àwùjo Yorùbá. Lára àwon onímò béè ni Ladélé àti àwon elegbé rè (1986:101-136), Dáramólá àti Jéjé (1975:34-48), Adèoyè (1979:219-239).

Àwon onímò wònyí so nípa ìgbésè kòòkan tó se pàtàkì ninú èto ìgbèyàwó Yorùbá, bèrè láti ibi ìfojúsode, ipa àti ipò alárinà, ìsíhùn tàbí ijóhen, ìtoro, ìdána, ètùtù ìyàwó, ìdí tí ìyàwó kò fi gbodò bá oko rè nílé, aso ìbálé, ògbògbò ìyàwó àti béè béè ló. Iyì nlá ni fún ìyàwó àti ebí ìyàwó, tí a bá bá ìyàwó nílè, èyí ni pé omobìnrin náà kò tíì bá okùnrin lò pò rí lójó ayé rè, ìnáwó òto sì ni èyí ninú èto ìgbéyàwó. Sùgbón ní òde-òní, èyí ti di àfiséyìn ti éégún n fiso, a ò kà á kún pàtàkì mó ninú èto ìgbèyáwó.

Ní gbàrà tí àwon òyìnbó amúnisìn bèrè ìsakóso èto ìsèlú ilè Nàìjíríá ni àwon pàtàkì ninú àsà àwon Yorùbá ti di àtèmérè. Lára ohun tí àkùdé bá ninú àsà wa ni èsìn, èto ìsèlú, èdè, àsà ìgbeyàwó, èyí tí a fé gbéyàwò ninú isé yìí.

Ní òde-oní, orísirísi ònà ni omokùnrin tí ó n wáya n gbà pàdé aya àfésónà rè. Òmíràn lè jé ilé ijó, inú okò, ilé-iwé tàbí ibi ayeye kan. Ònà miíràn tí ó tún gbòde kan nípasè ìsekáríayé ni orí èrò fóònù alágbèéká àti èro-aríhìn-ín-rohùnun-gbóhùn-eni (internet). Sé Yorùbá bò, wón ní aya tí a bá fijó, fé ìran ni yóò wò lo. Obìnrin tàbí okùnrin tí a kò mo ilé mo ònà rè tí a bá pàdé lórí èro-

aríhìnínrohùnún-gbóhùn-eni, tí wón sì fi béè di lóko-láya nínú ilé, ohunkóhun ni ó lè selè nígbàkugbà sí irú ìgbeyàwó béè.

Ní ìpele yìí, a ó wo àkóbá tí ìsekáríayé se fún àsà ìgbeyàwó Yorùbá lóde-òní, nípa síse àyèwò ewì àpilèko **Ayé n yípo** tí Àyángbilé àti Òpádòtun (2004) ko. Àwon akéwì yìí bu enu àté lu ojú àlàsódì tí àwon òdó òní là nípasè ìsekáríayé, èyí tí ó mú kí wón má ka àsà ìran babanlá won sí mó, tó jé pè àsà òyìnbó ni wón n mú yangàn. A rí èyí nínú ewì tí won pe àkolé rè ni "Ojú Àlàódì" pé:

Láyé ojósí kò sóhun tí won kì í bèwè se
Bèrè lórí isé ilú
Títí tó fi dórí nnkan ara ènìyàn...
Bíi ká fé síle
Bíi ká fé sin omo fóko
Anise tómo won bá fé lo sí ilé oko
Kò jo tàsikò yìí
Tóko kì í bá'yàwó è nílé mó
Àní kò jo tàsikò yìí tòmo odún
Mérìnlá n ponmo leeri
Ojoojúmó ohun àdáyébá n pare mó wa lójú lo
Ohun ìsènbáyé ò níyì mó
Ohun ta ti n gbé gègè tèlè télè
Kò jé nnkankan... (o.i.27)

Àwon akéwì yìí mú wa rántí àsà ìbára-eni-gbé-pò tó wà láwùjo Yorùbá télè (ese ikíní sí ikárùn un). Láti ese ìkefà, ni won mú wa lo sí àsà ìgbeyàwó, tí wòn so pàtàkì ìbálé ninú èto ìgbeyàwó, sùgbón tí o ti wá di ohun tí a kò kà sí mó. Wón so síwájú sí i pé:

Tó jé wí pé lásikò tí mò n sòrò rè
Gbogbo aya ni won máa n bá nílé
Èyí tí won ò bá bá nílé kì í níyì lódò oko
Yàtò sí èyí gégé bí enì tòbí è lábùkù ni... (o.i.27).

Ní àsìkò tí akéwì n so nípa ré yíí, ìwà àgbèrè kì í sohun àmúyangàn láwùjo Yorùbá, sùgbón lode oni, àgbèrè nínú ìgbeyàwó ti gbilè nínú òpò ebí, éyí ló mú kí akéwì so báyí nínú ewì tó pe àkolé rè ní "Àgbèrè ara" pé:

Ìwà àgbèrè ò wópò télè rí
Tàsìkò yìí kojá à n ròyìn
Nse nìwà àgbèrè túbò n pò sí i...
Àsìkò yìí la rénì tó ti níyàwó nílé
Tó tún n se súgà dadi káàkiri
Òpò sì làgbá ìyàwó tó n se súgá momì
Tó n mì rìyeríye kiri...
Ìgbà tágbà n séwó lomodé ò ní sèwó
Owó sísé wá dohun àmúyangàn láwùjo... (o.i. 49-51)

Yorùbá bò, wón ní òwú tí òbí (iyá) bá gbòn, lomo rè yóò ran. Sé omo tí ó ká igbá asèwó mó òbí ré lówó ni òun náà kò nì í gbé igbá owó sísé? Èyí ló fà á tí ó fi dàbí eni pé àsà yìí tí wá di ara àsà àwùjo Yorùbá béè sì ni ibi tí òlàjù bá wa dé ni.

Síwájú sí i, òpò òmò tí kò tí ì bàlágà ni wón tí gbé igbá isekúse, kí wón tó di eni tí n lóko tàbí tí n láya lóòdè. Akéwì kò sài fi èyí hàn báyìí

Èrù ò si mó omodé ti n síra won
Láso wò lójú òde
To jé wí pé láyé ojósí
Téèyàn ò bá fòngbàdì kó bàlágà
Bíi ki wón ó ti táyaá ní nílè
Bíi kí won ó ti délé oko ni
Kí won ó tó mohun tí n be lábé aso oníkálukú
Tàsìkò yìí ò rí béè
Kò séni tí wón n mò lódèdè mó
Ìta gbangba ni wón ti n mora won,

N ló se tígbèyàwó ò níyì mó,
Àbí ki lohun tí i bá tún gbayi
Nínú nnkan ta ti n bára eni se
Kó tó di páa féra eni síle... (o.i. 51)

Ohun tí akéwi n so níbi ni pé kò sí ìbèrù lára àwon òdò omo Yorùbá mó, ìsekúse ti di ohun àmúyàngan láwùjo. Òpò irú ìwà ìbàjè yìí ni ó jé orí èrò arìhìn-ín-róhun-un-gbóhùn-eni, ni àwon òdó omo Yorùbá ti n kó o. Béè sì ni ohun àmúyangàn ni ìwà yìí jé láàárín àwon òdó omo ilè aláwò funfun. Kèrèkèrè, imú elédè wo ogbà, ìwà burúkú yìí se béè gbilè láwùjo Yorùbá, èyí tí ó n se àkóbá nlá fún àsà ìgbéyàwó Yorùbá.

Àsà burúkú míiran tó tún wonú àsà ìgbéyàwò Yorùbá ní aso wíwò ní ojó ayeye ìgbeyàwó. Aso òfi ni a mò tó jé olórí aso tí oko àti ìyàwó máa n wò ní ojó ayeye ìgbeyàwó láwùjo Yorùbá àtijó. Sugbon òlàjú àti ísekáríayé ti yí i padà sí ìwoso ti àwon aláwò funfun.

Ní òdè-òní, tí omo Yorùbá bá n se ìgbeyàwó, ohun tí ó gbajúmò ni kí ìyàwó múra bí aséwó èbá ònà. Ohun tí Olódùmarè dá mó won lára gégé bi iyì àti èye omobìnrin ni won yóò fihàn sí gbangba fún òpò ènìyàn tó wà níbi ayeye láti rí. Ògèdè n bàjé, a ní ó n pón, irú ìwoso báyìí ni a fi n mo bí ìyàwó tàbí àwon òbí rè se gbajúmò ló láwùjo. Àpeere ìwoso béé ni akéwì fihàn nínú ewì tó pè ní "Àgbèrè ara" pé:

Olómoge ò so lèkè mó bárá ìdí mó
Ori ni wón tún fi n soge
Wón á so kobo mópàkó
Wón á sowó eyo mórí àtesè
Wón á sowó eyo méti aso
Egúngún ni mo mò ti n sòníní
So kobo mójú láyé ojósí
Olúbánbí ni mo rí tó máa n sowó
Eyo méti aso...
Àwòtélè ìyàwó tí kì í hàn télè rí
Ló wá dohun tí n hàn nísàlé
Ojoojumo lohun a dáyé bá n yípo... (o.i.49-50)

Kì í se pé akéwì n so àsodún, akùdé tó bá àsà ìgbèyàwó láwùjo Yorùbá òde-òní, nítorí a fé tè síbi ayé tè sí, ló n bu enu àté lù. Àwon ìwà ìbàjé wónyí ló n mú kí òpò ìgbeyàwó ní àwùjo Yorùbá lónìí máà máa tójó.

Àgbálogbábò

Ní àgbálogbábò, a tí se àgbéyèwò ohun tí àsà àti èrò ísekáríayé túmò sí. A sì fi ìdí rè mule pé kò sí bí a se lè ya àsà kúrò lára àwùjo, béè sì ní àwùjò kòòkan ló ní àsà tire tí ó wúlò fún ìdàgbàsókè àti ìtèsíwájú irú àwùjo béè. Àsà àwùjo kan kò dára ju ti àwùjo mìíràn lo.

Nínú àpilèko yìí ni a ti sàyèwò àkóbá tí ìsekáríayé ní lórí àsà Yorùbá, pàápàá àsà ìgbéyàwó, tí a sì bu enu àté lu èrò yìí (ìsekáríayé), nípa síse àyèwò ewì àpilèko **Ayé n yípo** tí Àyángbilé àti Òpádòtun ko.

Ní èrò tiwa, ibi tí ìsekáriayé se fún àsà àwon orílè-èdè adúláwò, pàápàá àwùjo Yorùbá, pò ju ire rè lo. Fún ìdí èyí, ì bá dára kí àwon Yorùbá tún èrò won pa, kí won padà sí àsà (pàápàá àsà ìgbèyàwó) tí ó mú iyì àti ògo bá ìran Yorùbá.

Àkójo Orúko Ìwé

Adeoye, C.L. (1979). *Àsà àti ìse Yorùbá*.Ibadan: Oxford University Press.

Adeyemi, L. (2006). *Ìmò Ìjìnlè Sáyénsì Nínú Àsà Yorùbá: Ìmò Ìtójú Àyíká gégé bí Àpeere*. A paper presented at the Annual National Conference of Yorùbá Studies Association of Nigeria (YSAN), held at the University of Ibadan, Ibadan, 7th-11th November 2006.

Àjàyí, B. (2001). Ìsèsé Yorùbá nínú Àjàyí, B. (Olóòtú) *Èkó Ìjìnlè Yorùbá: Èdá-Èdè, Lítírésò àti Àsà*, Ìjèbú-Òde: Shebiotimo publication, pp.107-131.

Anene, K. (2006). Social Change and Nigerian Heritage in Anikpo, M.O.C. & Atemie, J.D. (ed) *Nigerian Socio-cultural Heritage*. Port-Harcourt: Amethyst & Colleagues Publishers, pp.139-152.

Anthony, R.(2002).http://nuntia.cs.depaul:edu/webmissiology/Anthony.ttm

Atemie, J.D. & Girigiri, B.K. (2006). "The Concept of Culture" in Anikpo, M.O.C. & Atemie, J.D. (ed.) *Nigerian Socio-Cultural Heritage*. Port Harcourt: Amethyst & Colleagues Publishers, pp.1-13.

Ayangbile, S. àti Òpádótun, T. (2004). *Ayé N Yípo*. Abeokuta: Topdam Educational Publications Nigeria Ltd.

Daramola, O. àti Jeje, A. (1975). *Àwon Àsà àti Òrìsà Ilè Yorùbá*. Ibadan: Oníbon-ojé Press.

Encyclopedia Britannica (2007). Vol. 32, Encyclopedia Center.com.

Ladele, T.A.A. àti àwon egbé rè (1986). *Àkójopò Ìwádìí Ìjìnlè Àsà Yorùbá*. Lagos: Macmillan Nigeria Publishers Ltd.

The Guardian Newspaper (2007). *Globalization of legal services: Fears of African countries*, September 11, pp.84.